**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ẸLẸ́RÙ IBI, GBÉ ẸRÙ RẸ (3)**

**OṢÙ KARUN, ỌDÚN 2026**

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sí Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo aburú tí wọ́n ṣètò lòdì sí mi, padà sọ́dọ̀ ẹni tó ṣe ọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá mi, jẹ́ kí wàhálà ìkà padà sórí ẹni tó rán an, ní orúkọ Jésù.
7. Ètò ibi ìyówù tí wọ́n tú jáde lòdì sí ayé mi, padà sí ibi tí o ti ṣẹ̀ wá, ní orúkọ Jésù.
8. Olúwa, jẹ́ kí èrò onípá ṣubú sórí àwọn tó pilẹ̀ rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo wàhálà tí wọ́n rusókè nítorí mi, ṣàwárí ẹni tó ni ọ́, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí iṣẹ́ búburú padà pẹ̀lú ipá sọ́dọ̀ ẹni tó rán an, ní orúkọ Jésù.
11. Aburú ìyówù tó farasin sábẹ́ ètekéte, padà sórí ìkà, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí orí ìkà gbé ète rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ìpalára tí wọ́n ṣètò fún mi, padà gẹ́gẹ́ bí ìdájọ́ sórí àwọn tó ṣètò náà, ní orúkọ Jésù.

14. Olúwa, jẹ́ kí àyídáyidà búburú tapadà láìláánú, ní orúkọ Jésù.
15. Ààmì búburú ìyówù tí wọ́n fi sórí orúkọ mi, parẹ́, kí o sì tapadà, ní orúkọ Jésù.
16. Olúwa, jẹ́ kí okùn ìkà tú l'áṣirì, kí ó sì dójúti ìkà, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo irètí ìkà fún ayànmọ́ mi, kú lójijì, ní orúkọ Jésù.
18. Olúwa, jẹ́ kí ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ ìkà pa ìkà run, ní orúkọ Jésù.
19. Àjọyọ̀ búburú ìyówù tí wọ́n fùn ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo ète búburú tí wọ́n ṣètò nínú ìwà-ìkà fún ọjọ́ iwájú mi, wólulẹ̀ láì látunṣe, ní orúkọ Jésù.
21. Ìṣirò búburú ìyówù tí wọ́n ṣe fún ọjọ́ iwájú mi, pàdánù iṣẹ́ rẹ ráúráú, ní orúkọ Jésù.
22. Gbogbo ọwọ́ ìkà tó n rú wàhálà sókè fún ìlera mi, gba ìbáwí nípa ìdájọ́ àtokèwá, ní orúkọ Jésù.
23. Ayidayida buburu iyowu ti wọn ṣe lati dojuti mi, ki aṣiri rẹ tu, ki o si gba ijiya, ní orúkọ Jésù.
24. Gbogbo ìkórajọpọ̀ ibi tó lòdì sí ayànmọ́ mi, kùnà pátápátá, ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ ibi, tí wọ́n sọ láti rẹ ayànmọ́ mi sílẹ̀, padà nípa iná, ní orúkọ Jésù.
26. Àkọsílẹ̀ ibi ìyówù, tí wọ́n ṣe àṣepé rẹ̀ lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
27. Ìtúnramú-ogun ìyówù, tí wọ́n rán lòdì sí ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
28. Ọwọ́kọ́wọ́ ibi tó n rú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ dìde lòdì sí ojúrere mi, pàdánù iṣàkóso rẹ, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo pámpẹ́ búburú tí wọ́n kẹ́ lòdì sí idìde mi, yípadà, kí o sì mú ẹni tóni ọ́ nígbèkùn, ní orúkọ Jésù.
30. Ètekéte ibi tó n lépa ayé mi, mú ẹni tóni ọ́ so, ní orúkọ Jésù.
31. Gbogbo ìwà-ìkà ìkọ̀kọ̀, tó n ṣagbátẹ̀rù ìgbóguntì lòdì sí ayànmọ́ mi, kí àṣírí rẹ tú, kí o sì wólulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
32. Májẹ̀mú ibi ìyówù, tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, fọ́, kí o sì wọnú ìdè padà, ní orúkọ Jésù.

33. Àwọ̀n búburú ìyówù, tí wọ́n dàbò ìdílé mi, f'àya, kí o sì mú àwọn tóni ọ́, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo ètò òkùnkùn tó farasin sábẹ́ ẹ̀rìn, láti mú idàrúdápọ̀ bá ayànmọ́ mi, kí àṣírí rẹ tú, kí o sì gba ìdájọ́, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo àkọsílẹ̀ búburú, tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ìpele mi tókàn, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
36. Ètò sátánì ìyówù, tí wọ́n fi ìwà-ìkà gbéró láti mú ìjákulẹ̀ bá ìpele mi tókàn, túká báyìí, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo ìwà-ìkà tí wọ́n ṣètò sí ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
38. Gbogbo ẹnu tí ìwà-ìkà rólágbára lòdì sí ayànmọ́ mi, kí òtítọ́ pa ọ́ lẹ́nu mọ́, ní orúkọ Jésù.
39. Ọwọ́kọ́wọ́ ibi, tí wọ́n nà lòdì sí ọ̀pá oúnjẹ mi, gbẹ báyìí, ní orúkọ Jésù.
40. Gbogbo pẹpẹ búburú, tó n ṣiṣẹ́ ìránṣẹ́ ìkùnà sínú ayé mi, gb'iná, ní orúkọ Jésù.